# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ORẸ AIYE TẸNI GBOGBO LAWA

NO 1,592 WEDNESDAY DECEMBER 22 1965 (2D)


## Ile Igbimo Apapo Ijoba Fẹ Ṣe Ipade

EKO:- Ni kutukutu Owurọ ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kokanlelogun osu yi ni irohin de ile iṣẹ wa lati ile iṣẹ Minista Alamojuto eto irohin fun apapọ Ijọba Naijiria pe awọn ọmọ Ile Igbimọ Aṣofin Apapọ Ijọba ilẹ Naijiria yio bẹrẹ ipade-ọdun titun eyiti iṣe 1966 ni ọjọ kejila oṣu to mbọ yi.

Irohin na tun fi ye wa pe ni deede agogo mẹwa Owurọ ni ẹsẹ gbogbo awọn ọmọ Ile Igbimọ na yio ti pe si Ile Igbimọ Aṣofin apapọ Ijọba Naijiria lati bẹrẹ eto ipade titun na ni ọjọ na.

Bakanna ni irohin na tun fi ye wa pe awọn Igbimọ agba oṣelu eyiti a npe ni (Senate) yio tun bẹrẹ ipade ti wọn ni ọjọ kẹtala Oṣu kini ọdun to mbọ yi ninu Ile Igbimọ awọn agba Oṣelu.

Irohin na tun ṣe afikun pe ni deede agogo mẹwa owurọ ọjọ na ni awọn ọmọ Ile Igbimọ agba Oṣelu yio bẹrẹ ipade ti wọn ni ọjọ na.

Ṣugbọn irohin ko ti fi ye wa ohunti awọn ọmọ Ile Igbimọ mejeji na yio jinroro le lori tabi iru Ofin ti nwọn yio gbe jade ni ọjọ na.

# OLOYE AWOLỌWỌ DI ẸNITI GBOGBO AIYE NFẸ

KALABA:—Ni ọjọ Aje ti iṣe ogunjọ oṣu yi ni gbogbo awọn Asiwaju Ijọ Ọlọrun yika gbogbo Ipinlẹ Iwọ Orun Naijira ati Eko pẹlu awọn Ọba ati Ijoye lọ si Kalaba ni nwọn si lọ ba Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, Olori ẹgbẹ Afẹnifẹre, ẹni'i o wa ni ọgba ẹwọn ni Kalaba nisisiyi lati lọ bere ohunti awọn ba le ṣe si ọrọ ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ti gbogbo rogbodiya ti o wa ni Ipinlẹ na nisisiyi yio fi de opin.

Irohin ti a ri gba lati ilu Kalaba lati ọdọ Onlwe Irohin wa fi ye wa pe, ni ibẹrẹ osẹ yi ni awọn enia na de si ilu Kalaba ti nwọn si sọ fun awọn Oluṣọgba ẹwọn na wipe ki nwọn fun awọn ni aye nitoripe awọn nfẹ lati ri Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ kia kia lori ọrọ kan eyiti o ṣe pataki pupọ.

A gbọ pe lẹhin ọpọlọpọ alaye, awọn Oluṣọgba na gba fun wọn lati lọ fi eju kan Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ nibiti o gbe wa ninu ọgba ẹwọn na.

A gbọ pe inu awọn enia na dun lọpọlọpọ nigbati nwọn ri iru aye ti Oloye Awolọwọ wa ninu ọgba ẹwọn na.

Nigbati awọn enia na ṣe akiyesi Oloye Awolọwọ, daada nwọn rii wipe, Oloye Awolọwọ ko tilẹ yipada rara, bi o ti ṣe wa tẹlẹ na ni o tun wa lati ọjọ yi, ṣugbọn ohun kan ti awọn enia na ṣe akiyesi ni wipe, nṣe ni awọ ara Oloye Awolọwọ tun ndan gẹgẹbi awọ - ara ọmọ tuntun, ti oju rẹ si tun dabi oju ọdọmọde ti o tutu yọyọ.

Nigbati awọn enia na de ọdọ rẹ, nwọn ṣe alaye ohunti nwọn wa ri Oloye Awolọwọ fun, nwọn tun sọ wipe, lati Eko ati Ipinle Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ni gbogbo awọn ti wa Nitoripe, lati igbati Oloye Awo-

WO OJU EWE KẸFA



Oloye Obafẹmi Awolowo
OLORI ẸGBẸ AFẸNIFẸRẸ

## Akiyesi Pataki

Eyini lati kede fun gbogbo ẹnyin Musulumi jakejado orilẹ-ede ilẹ Naijiria ati paapajulọ ẹyin Onkawe wa gbogbo wipe (NAFILA) osu Aawẹ yio bẹrẹsi maa jade ninu Iwe Irohin Imọlẹ lati ọla lọ

Iwọ Musulumi ti o fẹ lati maa mọ awọn Nafila osu Aawẹ, nṣe gbagbe wipe gbogbo ẹna ti o le gba maa kirun rẹ ni yio jade ninu Iwe wa lati ọla lọ

Ẹ ku ọdun Aawẹ o ki Allah jẹki emi ti o bere Aawẹ na le gba Aawẹ na jan.

OLOTU

# ITAN IGBESI AIYE ỌLỌLA HAKIM AHSON

## Eniti Işe Asoju Ijọba Orilẹ-Ede Pakistan ni Naijiria

Lẹnulọlọyi ni Irohin kan de si ile işẹ wa lati Ile i e Asoju Ijọba Oril ede ile Pakiat n ni Naijiri ni nomba 26, Catholic Misson Street, wipe, Olọla Dọkita Hakim M. Ahson, eni odun meri dinladọta ni Asọju Ijọba Orilẹ ede ilẹ Naijiri nisisiyi ti o si ti bere işẹ r ti Naijiria ninu odun ti o kọja lọ yi. t wọn si tun fi hunsokan wipe Dokita Ahson ni wọn fe gẹgẹbi Mayo ilu na.

Ọgbẹni H A Chia'i, eniti işe akọwe eto Irohin fun ile işẹ Ijọba Orile ede ilẹ pakistan ni Naijiria so fun Oniwe Irohin wa ni ibere osu yi wipe, ni ọjọ kejidinlogun osu kokanla odun ti o kọja lọ yi ni Ọlọla Hakin M. Ahson de si Orilẹ ede ilẹ Naijiria lati wa gba aye ise Asoju Ijọba Orile ede ilẹ Pakistan ni Naijiria nigbati eniti o ti wa ni aye na tele ti t pari işe ti e ti si ti pada lọ si ile.

Gẹgẹbi alaye ti Ọgbẹni H A Chia i şe fun Oniwe Irohin wa ninu ile işẹ wa n a gbọ wipe, ise Dokita ni Ọlọla Ahson ti nşe tele ni ilu wọn ki nwọn to yan an si aye ise Asoju Ijọba ninu ilu wọn.

Ọmọ ilu kan ti nwọn pe ni Sind ni Pakistan ni Ọlọla Ahson se, nipe ninu ọdun 1918 ni nwọn bi Ọlọla Ahson ninu ilu wọn, ni Ipl lẹ Iha Iwọ Orun ilẹ Pakistan.

Nigbati o ti wa ni ọmọde ni o ti bẹrẹsi ma sẹ ise Oşelu eyiti Baba rẹ nşe ni gbati nwọn fi bi ninu ilu ni ninu ọdun 1819, şugbon ko pẹ pupọ lẹhin akitiyan ati Isala re ti awọn ọmọ ẹgbẹ kan ninu ilu na fi yan an gẹgẹbi Olori wọn gẹgẹ bi akitiyan ati aiya ti o ni ninu gbogbo awọn ohun ti o ba ti jẹ ti a ọn ọmọ ẹgbẹ na ninu ilu wọn.

Ninu ẹgbẹ ti o wa ti o si ntọju awọn ọmọ ẹgbẹ na ti awọn Aşiwaju ẹgbẹ Oşelu ilu wọn ti nwọn si se akiyesi gbogbo bi o ti se ise fun awọn ẹgbẹ na.

Nipa işẹ rẹ yi, ni awọn Aşiwaju ẹgbẹ Oselu ti si ri, ti nwọn si nse akiyesi gbogbo awọn ohun ti o nse nigbati nwọn si ri wipe eniti o le ma tọju awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ bayi ti bere owo lowo wọn ni awọn enia na ba re lọ pe wipe ki o wa lo gbogbo ogbọn re fun ilosiwaju ati idagbasoke awọn ara ilu rẹ ninu ẹgbẹ Oselu eyiti Baba rẹ na gbaba fun gbogbo awọn ara ilu.



**Dokita Hakim M. Ahson**

Asoju Ijọba Orilẹ ede ilẹ Pakistan ni Naijiria

Akitiyan ti Ọlọla Ahson ni yi, ko ya gbogbo awọn ara ilu na lenu pupọ nitori pe awọn enia ti nwọn mo Baba re ni nwọn ro wipe, gbogbo ohun ti o mo, Baba re ni o fi ko.

Şugbon ko pe pupọ lẹhin eleyi ni Baba re ku lehin igbati o ti fi opol po igbesi aiye re se wahala lori idagbasoke ati ilọsiwaju ise ilu re Pakistan.

Şugbọn nigbogbo igbati awọn enia fi upa Ọlọla Ahson wipe ki o wa si ẹgbẹ Oselu yi, ise Dokita ro in o nse lo on pupọ ni ni ile wosan fun ra're nibiti o gbe tọju awọn alaisan ninu ilu Pakistan.

Nigbati yio si tun gbe Iyawo eniti o jẹ gbe ni Iyawo Dokita ni Obirin na ti on na si mo ise re ni oju mejeji Nigbati o je wipe Dokita Ahson ni Ile Iwosan aladani nibiti o gba ti nto awon Alaisan ni awọn re ni ba ber si ma se ise ninu ile iwosan na lehin ti awọn gbe Iyawo tan awọn mejeji si jọ jo nşe n nu ile Iwosan na.

Şugbon nigbati o di inu ọdun 1947, ti nwọn le e bo ninu ilu wọn ni Sind, awọn ara ilu na yan gẹgẹbi Asoju wọn ti nwọn yio dibo fun nigbana, şugbọn Dokita Ahson wọle ninu ibo na lai si osi alatako kankan fun un ninu ọdun na yi.

Nigbati nwọn dibo na tan ni ọjọ kẹrin ti awọn ọmọ Ile Igbimọ na yi ko se ipade gbogbo awọn Asoju ti nwọn wole ninu ibo na ni nwọn pa ohun po

Nigbati nwọn si tun dibo ile Igbimọ na eniti nwọn fẹ lati yan si aye Mayo inu ilu na, Dokita Ahson lo wọle, nwọn si yan an gẹgẹbi Mayo Ijọba ipinlẹ Ibinlẹ ilu na ninu ọdun 1947.

Lẹhin igbati o ti di Mayo ilu Karachi tan ninu ọdun 1947, ti nwọn nlo si Ipade kan ni orilẹ ede ile Amerika ninu ọdun 1948, Dokita Ahson yi ka ọkan ti işe Mayo ilu Karachi ni gbogbo awọn ọmọ ile Igbimọ na yan wipe ki o lọ si ipade ti awọn Alase Ijọba orile ede Amẹrika, o si lọ si ipade na.

Lẹhin eleyi, fun odidi ọdun mẹrin ni awọn ẹ ta na fi nyan an gẹgẹbi Asoju won ninu ipade ti nwọn nse ni orilẹ ede Faranse ati gbogbo awọn ipade miran ti nwọn tun nse ni orilẹ ede ilẹ Amẹrika.

Nigbati o di igba kẹrin ti nwọn tun nlo si ipade ni ilẹ Amẹrika, ni awọn Asoju ipade ti nwọn nlo se ipade na ni Amẹrika ni on turu ilẹ b t n yan Dokita Ahson ni igbakeji Alaga ipade ti nwọn şe.

Nigbati wọn si tun lọ si ipade na ninu ọdun 1953 awọn Igbimọ ti nwọn yan lati maa se eto ti nwọn yio ti maa se akosilẹ eto işẹ ti awọn Asoju ipade na yio maa se ni ọjọ iwaju tun yan Dokita Ahson wipe ki o jẹ ọkan ninu awọn Igbimọ ti yo maa se eto pade ti awọn nşe ninu ilu Amẹrika.

Gbogbo igbe e ati ilọsiwaju ti Dokita Ahson ori lati awọn ijọba Alagbara orilẹ ede aiye yi jẹ ohun iwuri fun gbogbo awọn ara ilu Pakistan, ti inu wọn n dun wipe awọn ni ti Asoju ninu Igbimọ ti nwọn nşe eto fun idagbasoke ati Isẹkan orilẹ ede aiye, awọn si tun ni ọmọ ninu Ile Igbimọ n pọlu fun igba kini ninu orilẹ ede Pakistan.

Nigbati o tun di inu ọdun 1965 ni awọn ara ilu na ba tun yan Dokita Ahson ni

WO OJU EWE KARUN

# Egbe Demo Se Ipade Lori Gomina Iwo Orun

IBADAN.- Awon ogunnagbongbo omo egbe Demo ti bere ipade asetunse ni Ibadan lati wa ona ti nwon yio fi iya je Gomina Ipinl. Iwo Orun Olola Oceleye Fadahunsi, lori iwa ti egbe Demo ni Gomina na hu si ijoba egbe awon, nwon ni awon ko mo ohunti Gomina ti tebe ti o fi wa ru sewo. ninu ipade nwon ni won ti ese ero a ti yo Gomina lori wipe, ko wa si ile Igbimo sofin ni ojo ojo 'Bo tise ojo kesan osu yi.

Gegebi oro ti awo minista Demo nso ni nwon ti so ye ohunti awon ro lokan ni wipe boya lori ibo magomago ti awon eni Ipinle Iwo Or nn di ni ojo k kanla osu kewa odun yi lomu ti Gomina na ko fi wa ba awona si ipade Igbimo Asofin.

Nwon tun so ninu ipade na pe awon lero pe, Olola Fadahunsi ti fe fihan pe on koni ba awon so wopo lori Ijoba egbe Demo tiwon fese lolo ni ojo kokanla osu kewa odun yi.

Ninu ipade awon enia pataki pataki omo egbe Demo ni awon tise ipinnu pe, aw n yio fi iya ese re je nitoripe eniti o ba ta oja erupe o ni lati gba owo okuta

Irohin ipade na so pe gbogbo won ko fi oro se okan lati yo Gomina na, awon omo Ijesha to wa ninu ipade ni so pe, o ye ki awon jeki Gomina na ki o pari odun marun re ki awon to yo kuro ni ipo Gomina Ipinle Iwo Orun patapata. Ninu ipade na ni nwon tun wa ona lati fi ese Olola Alaiyeluwa Oba Adesoji Aderemi Oni ilu Ife gun oiu na loju, itoripe Oba Aderemi ko wa si ipade awon lobaloba n ojo kesan osu yi

Irohin na tun so pe egbe Demo so ninu ipade nwon na pe, awon yio wa ona lati fiya je Oba Aderemi Oni ti Ile Ife ati awon Oba ti ko wa si ipade awon lobaloba lojo na, a tun gbo wipe gbogbo awon oba ti ko wa si ipade lobaloba ni awon egbe Demo ti nko oruko won sinu iwe kan lati mo iye won.

Nwon tun fi ari si awon Oba ti ko ran won lowo lasiko ibo madaru ti nwon di koju ni Ipinle Iwo Orun,

Ninu awon oba ti nwon ti ami si oruko won ni awon oba meta ni agbegbe Oshun, oba meji ni agbegbe Egba, oba kan ni agbegbe Egbado ati oba kan ni agbegbe Ibadan,

A si nyogbo pe Owa ilu Igbajo, Oba Famodu yio je okan ninu Oba ti o wa ni agbegbe Oshun ti Ijoba egbe Demo yio fun ni minista ti ko ni ise


## ALEBIOSU BOOKSHOP

13 BAMGBOSE STREET, PHONE (21304) LAGOS

LADIES & GENTLEMEN/

As your problem is ours, therefore we have got in Stock, Seasonal Lovely & Interesting Xmas Cheque and Xmas Cards in assorted types as:-

| | | | |
|---|---|---|---|
| 1 | To my Darling | 2 | To my Sweet Heart |
| 3 | ,, my Lover | 4 | ,, One I Love most |
| 5 | ,, my Boy Friend | 6 | ,, my Husband |
| 7 | ,, my Wife | 8 | ,, my Sister |
| 9 | ,, Brother | 10 | ,, my Friend |

You will be mostly impressed if you come to the above named Bookshop for your Seasonal Greeting Cheques & Xmas Cards,

WISHING YOU HAPPY CHRISTMAS IN ADVANCE


**E maa ka Iwe Irohin Imole Ki e si maa Polowo Oja yin sinu re Lojojumo**


## Ila Kini eleyi o




OGUN A PA YANMU — YANMU
LORI ERIN META NI

Three Elephant Brand mosquito coils d ra pupo An O dara ju gbogbo ogun a pa yanmuyanmu yoku l.

O npa yanmuyanmu ninu ile n kiakia orun re si da ra pupo ju gbogbo ogun yanmuyanmu yoku lo Bakanna ni o si tu yara na ayin ati idun

Tete lo ra packet ogun yanmuyanmu Three Elephant Brand coils tire loni, ki o si d w , iwo yio ri bi o ti se pa gbogbo yanmuyanmu inu ile re ti iwo ati awo omo re y o si sun d radara

Ki o ri d ju pe ogun yanmuyanmu o ri erin meta y u nwon mu un o

Three Elephant mosquito Brand coils yi wa ni sobu eitaja kakiri orile ede yi

DISTRIBUTORS
AMOS GBENLE & BROTHERS
34, Decemo Street, Lagos
6 & 11 Balogun Street, West
LAGOS

BERE FUN OJULOWO ADI-ELEGBO

## "Congreve's odo Form--Ointment'



Atomatase ni egbog " ADI-ELEGBO" yi i fun itoju gbo bo orisirisi "EGBO—ESE" ni kiakia bi o ti wun ki jo re ti le pe to, Adie egbo yi ko ni egbe nipa wipe awo ko idoti ni bi er gbogbo ti ba wa loja egbo patapata jade oju re yio si mo daradara .Lehinna oju egbo ti o ba jin sinu yio jeki oju to ru wa soke, yio si pon daradara run bakuru ko si mo werewere ni yio si san patapata. Alafia de si o niyen :

Ri daju ghangba wipe awon sobu ti a da oruko won si isale iwe yi ni egbe ranse lo ra Bibeko awon Eleru tabi onijibiti yio ta 'Adamodi' re fun o mase gba e ra O.

Bere egbog yin sobu awon :—o

LAGOS ISLAND CHEMIST
Victoria Street, Lagos

UNITED DRUG CHEMIST
Alli Street, Lagos.

# NWON TUN PA ENIA MERIN NI SHAGAMU

SHAGAMU- Gbogbo enia to wa ni ilu Shagamu lo bẹrẹsi sare Ọlọmọ ngbomo gbọn ti olukuluku bẹresi ti ilẹkun mọri nigbati ja nla kan be silẹ larin awọn enia ilu Shagamu ati awọn ọmọ ẹgbẹ Olomi (NPC) ti nwọn jẹ Hausa to ngbe ni adagbo kan ti nwọn npe ni sabo, Shagamu ni d eede ag go mẹwa ku işeju mẹwa alẹ ọjọ Abamẹta ti işe ọjọ kejidinlogun oşu yi titi di ojo Aiku ti işe ọjọ kọkandinlogun oşu yi eyiti enia mẹrin tun padanu ẹmi wọn ninu ija nla to bẹsilẹ larin awọn enia na

Oku enia meji ni awọn olopa ti gbe ni owurọ ọjọ Aiku ti işẹ ọjọ kọkandin-logun oşu yi ninu awon mẹrin ti o padanu emi won ninu ija nla to bẹ silẹ na eyiti o jẹ wipe ni adugbo sabo ni ilu Shagamu eyiti işẹ adugbo ti awọn Hausa na ngbe.

Irohin tun fi ye wa pe won olopa to ri oku enia meji na gbe ni a gbọ wipe nwọn ti gbe wọn lọ si ile wosan ti lakọọkọ ti ilu Shagamu lati lọ şe ayẹwo wọn.

Ninu awọn enia mẹrin ti nwọn padanu emi won ninu ija nla to bẹ silẹ na ni oniwe Irohin wa fi ye wa pe nwọn ti mu oruko enkan ninu won eyiti işe Bakare Adisa ati pe nwọn ko ti mo awọn enia mẹta to ku na.

Irohin fi ye wa pe Ọgbẹni Bakare Adisa-la jije nja. de lọ pẹlu Ọgbeni Odulaja eyiti o je okan ninu Olori egbe oşelu ki nwon to pa Ọgbeni Adisa

Şugbọn owọ ko ri bi tẹ Ọgbẹni Odulaja pupọ şugbọn irohin fi ye wa pe o fi ara gbogbẹ eyiti o jẹ wipe nwọn ti gbe lọ si ile Iwo-san lakulaku nibi ti o ti wa ninu kakukala bayi

Oniwe irohin wa tun şe alaye pe gbogbo awọn mọ to ti o ngba oju arin ilu Shagamu lati ilu Eko lọ si Ijẹbu Ode Ibadan ati Ibinni ni irohin fi ye wa pe nwọn ko ri ona gba kọja ati pe gbogbo awọn moto na ni awọn enia na nda duro ti nwọn tun kọlu ọpọlọpọ ninu awon mọto ati enia inu rẹ pẹlu.

Bakanna ni awọn enia na ti nwọn jẹ janduku ọmọ ẹgbe Oşelu tun lọ kọlu ọpọlọpọ ile ninu ilu na eyiti o jẹ pe nwọn si dana sun ile miran titi o fi jo di eeru tabi pe ki nwọn ba gbogbo inu ile na jẹ eyiti ko le şe tun şe.

Ọpọlọpọ awọn enia ti nwọn wo mọto gba arin ilu Ijẹbu Ode ati Shagamu ni o jẹ wipe, awọn janduku lọ kolu, a tun gbọ pe awọn enia na ti fi ọrọ na sun awọn Olopa.

Irohin fi ye wa pe awọn janduku na tun lọ kọlu Oyinbo kan pẹlu awọn ọbi re ninu moto re eyiti o jẹ wipe nwọn da duro ni ilu Shagamu ti nwọn si ngbo-gbo ẹru won titi awon Oyinbo na fi wo moto takisi lati sa asala fun ẹmi wọn lọ si Ijẹbu Ode

Bakanna ni irohin tun fi ye wa pe awọn enia na tun kolu moto boosi kan eyiti ero to ko jẹ marundinla-dorun (65) ati pe awon enia na si o moto Boosi na titi o fi di eeru eyit o jẹ wipe awon ero inu moto na si tun fi ara gbogbẹ ngbati awon nsa asala fun ẹmi won,

Oniwe irohin wa tun fi ye wa pe ilu Shagamu si tun jẹ ilu kan ti Ogbara ẹjẹ i bẹresi san bi omi ojo lati ọsẹ to kọja eyiti okẹ-aimoye ohun ini ti padanu ninu ina tabi pe ki nwon si ba jẹ patapata,

# YE IRAWO RE WO

AQUARIUS (Jan 22-Feb 20) Ọpọlọpọ nkan iyanu ni iwọ yio ri loni, nitorina ki o ma gbaradi fun ohunkohun ti o le de, awọn işẹ ti o jẹ pataki ni ki o kọkọ yanju bi o ba ti de ibi işẹ, lowurọ

PISCES (Feb 21- Mar 20) Şugbọn loni, alafia yio to ara tobẹ ti o jẹ wipe gbogbo işẹ ti iwọ ko tiise şe ri, ni iwọ yio ma şe, iwọ yio şe awọn işẹ na ni aşeyanri kedere.

ARIES (Mar 21-April 20) Irorun ni gbogbo ọjọ oni yio jẹ fun o, ohun gbogbo ti o ba ni şe yio ma tẹ o lorun, mura ki o ran ara rẹ se, fun ilosiwaju, nipa ohun ti o ngbero ninu okan rẹ.

TAURUS (April 21 May 20) Maşe fi ara ale fun aarẹ ti o fẹ yọ o lẹnu ki o si ni ogbon inu nitori ẹnikan nibẹ ti yio maşe lara rẹ si ma funra si o eyi dara pupo

GEMINI May 21 June 21 Ọpọlọpo ohunti o jẹ işo-ro fun o ni iwo yio le yanju patapata ti yio ri fun o aitẹ lorun iwo yio si gburo oro kan lati odo ajoji enia kan

CANCER (June 22 July 22] Iwọ yio mọ ni ara rẹ wipe a ti gbe ẹru nla kan kuro ni ejika rẹ, tobẹ ti ara rẹ yio ya lati şe işekişe.

LEO (July 23 Aug 22) Ijọgbọn kan si mbẹ nilẹ ti o nfẹ amojuto ni owurọ yi, şugbọn ki o maşe ko ibi ara si nitoripe ti ela ni yio şoro, maşe ti lo gbogbo ogbon ori rẹ silẹ tan.

VIRGO [Aug 23 Sept 23) Ire yio kan o lara ni owuro yi, şugbọn igbati osan yio ba fi po, ... arẹ le de si o, ohun ... ohun ti ... b si lo s, alafia yio de.

LIBRA (Sept 24 Oc. 23) Ire mbẹ rẹpẹt, loni, ti yio si tẹ lorun pe okan rẹ bakanna ni yio ri ni akoko sa şe jeje nibi işẹ rẹ ki o si jẹki ero ori rẹ pe.

SAGITTARIUS (Nov23-Dec 21) Ire mbẹ fun oro abẹ ile şe loni, mura ki o si ... se toju ipalemo odun Keresimesi ki o si ... pe awon enia ti yio wa ba o se ayẹyẹ na, iwe ... ki ... ko si nkan.

CAPRICORN (Dec 22-Jan 21) Dupẹ fun osupa rẹ ti o ntan imọlẹ alafia yio to lowo ko si ni ri ikolu buruku, todo awon ore re ni ki o lo gbogbo nkan yio sile olorun.


# ... EGBOGI JẸDIJẸDI

BERE FUN EGBOGI

## "CYCLEVEN"

Arun Jẹdijẹdi jẹ okan ninu aimodi ti o buru ni patak fun Ọkunrin ti o si lagbara lati şe iwosan rẹ patapata

Ọpọlọpọ egbogi ni nwọn nta kakiri odẹ nisisiyi ti wọn a ma polowo wọn fun iwosan rẹ şugbọn boya la le ri mẹwa ninu ogorun ti o le şe iwosan arun yi daradara. Awọn ẹlomiran lero wipeboya bi awọn ba lọ si ile Dokita lati lo ke eyiti o ba nyo jade lati omusu ku ni. pa bẹ awon o bo lowo rẹ palapata

Şugbọn awa ko ro bẹ rara: Lẹnin odun diẹ iyonu rẹ yio si tun ma bẹrẹ bakanna, Orisirişi Jẹdijẹdi ni o wa keini ti o bẹrẹ nipa aiko ma şe igbonse dede tabi lojo-jumo, elomiran nipa ijoko ni ojukanna selu lojojumọ tabi gigun keke ylogere (Basikulu) pupo elomiran ewe nipa ije Şuga tabi oniruru ohun adidun pupo ju. Jedije-di orişirişi ni o wa ewo ni tirẹ? Bi o ba nyo jade ninu olusu tabi ti o ba nmu wa lẹhin igbonsẹ tabi ba nyo ti o ba şe igbonsẹ tan ni, tabi ti nrin o ninu musu ni eyikeyi ti o bara bere egboki "CYCLOVEN" ti awọn ... nbo Jamani fere wa id rẹ ko ki o si d nwo o işi mẹ-na yio daju wipe iwo yio bo low Je ... p tapatarslaona yio de s i ekeji re ko si ninu gbogo begbogi or lu Nsira Bere re ni:—

Waterloo Medecine Stores
8 Palm Church Street Lapos P O Box 333

NIGERIAN MEDICINE STORE
4, Tinubu Square Lagos

# Itan Igbesi Aiye Ahson

**Lati Oju Ewe Keji**

Gomina, awon si tun yan wi e ki o maa se akowe Igbimo Ile eko nla Unifas ti Kancrlah ti ile eko nla Un fasiti Sind.

Ise yi ti Dokita Asoo rs ni u ile re sugb n ni gbogbo ig ti o fi se awo ise wo i ti awo ara ilu Pakistan yan a l e ki maa se. Iya o re ko fi i ba ka fi Ile Iwosan won sile. Iyawo yi lo s se awon Ise Dokita lo ni u ile wo san wo, ti ko jeki ise n d r n gb ti awon ara ilu Pakia a ya o e re si ise idagbas ke ile sugb n nigbati ise n fe po ju ohun ti Iyawo re nika l sa lo. ew n gb awon Dokita miran b medogun ti n so t n nse ise n n Ile Iwo san na ti nwon si nwon ow f n gbogbo won ni ipari osu gegebi ise won.

Sug on nigbati o di osu kokanla odu 1964, ni nwon ba tun yan Dokita Ahson ni As ju Ijoba Orile ede ile Pakistan ni Naijiria wipe ki o ma a wa se Ise nibe, nigbati o nbo iyawo re ati awon omo re ni nwon jijo wa si Naijiria, sugbon nigbati o di ibere odun yi, ni Iyawo na ba pada lo si ilu won lati maa lo mojuto awon Dokita ti nwon nsise ninu ile Iwosan.

Sugbon nigbati o di inu odun yi ni Iyawo re ba pada si ilu won ni Paks t n lati maa lo mo juto awon Dok t ti n on gb si Ile I osa won ni ile awon omo won miran si wa ni ile pelu iya won ti nwon nlo si ile iwe.

N gbat Olola Ahson de si Naijiria o ti se ibewo lo si awon agbe be kan lati lo wo bi awon enia Orile ede yi ti se ngni ilosiwaju si ati b Ile N ijiria ti se ri.

A gb wipe ni opin ibere odun ti nbo yi, Olola Ahson yio tun se ibewo lo yika gbogbo igun merer in Orile ede Naijiria lati lo ki awon Gomina Ipinle ati awon A'akoso Ijoba Ipinle k okan.

Ijoba Orile ede Pakistan ti fun opol p awon omo Naijiria ni ebu eko ofe lati l ko iwe ni Unifasiti ilu w n, n nu awo ise ti awon omo ile Naijiria nlo ko ni ilu Pakista ni Ise Oluko, Ise Soj Ise Olopa ati ise Imojuto re

Bakanna ewe, ni nwon ti ba fun awon omo Naijiria ni ebun eko-ofe nipa jise a be ise Apoogun, a gbo wipe awon omo Orile ede ile Najiri ti nwon wa ni ile P kist n n sisiyi le ni igb eni, ti Olorun nu w n padi wa si ile I yo ati alafia o

Nigb ti Oniwe Irohin wa l fi o u kan Aso ju Ijoba Orile ede ile Pakistan na, Olola H s m M Ahson ni u ile ise r, Olola na s wipe Orile ede on ti se eto m ran sile nisisiyi lati ran l b Naijiria lo wo nin g og i law e ise idagbaso e ati il si waju s bon og n ati edeaiye le k n t o b sile lar n aw n aw n enia inu ilu o ati awon e ia ile l d a ko je i eto na le ti eori nisisiyi, sugbon bi edeaiyede na ba le pari, gbogbo oh ti awon ti se eto re s le lati se fun Naijir a ni Ijoba on y o se p tapat .

O wa gbadura wipe, ki Allah le j ki ed aiyede na le pari layo ati alafia ki o si da'wo og n dno larin awon or l, ede mejeji na

O t n wa dupe l wo gbogbo awon enia ti nwon ti l wo ninu oro na wipe ki edeaiyede na le tete pari awon t Olola na se ape juwe won gekebi onilaja.

Ni u won ni Alhaji Abubakara Tafawa Balewa Al koso Apap Ijoba Naijiri o t n wa so bayi wipe eniti o fi ture s le ti o ngbo t eni, Oluwa i yio ma a gbo ti Oluware na

Ni ipari oro re, Olola Ahson so wipe; "Iboukun ni fu awo Oa laja nit i o n Ol r n ni ao maa pe won."

---

## WANTED

Advance, Apprentice and Apprentice Printers.

Apply In Person

Irohin Imole's Office

16, Bi nabosi Street LAGOS

# Kere o Kere o! Akiyesi Pataki




Awa na le jeri wipe Ojulowo h nunh nun Egbogi n LEOPILLS awa na nlo ni Gold Coast (A kara Gha a pelu meji re ko s ninu gbogbo oris risi Egb gi t o w ni Ile Naijiria

A wa na ewo ni igb ro Ilu Eko, Irohin ti o wa lenu gbogbo enia tomode t'agba ni asiko yi ti n w n fi se oro ati orin larin ara won nipa Egbogi Jamani olokiki yi ti n pon ope ni LEOPILLS

Imoran awon Dokit Oyinb ti nwon nse iwadi Egbogi LEOPILLS, yi kan so wipe bi o ti lagbara to ati bo je Ojulowo giriki ati atamatase fun "JEDIJEDI" bi o ti wu ki ojo re pe to be na ni nwon si tun fi owo soya tabi po ile i fun gbo bo awon ti am di tabi iju, Igbe sise, siko ri igb nse deede, inu irun n gb ku ta ara wiwo, Esa ri ehin didun s sa ati aiko rran kede e ko d ro baruku ara, aisan Onigb meji ati orisirisi arun miran gbogbo pelu

"Wipe awon yio ri alafia ni ki ejak ti n on nba egbogi LEOPILLS nitoripe o tun ma tun eje se enia nipa sis d otun.

RANTI PE ALAFIA LOGUN ORO IJAFARA SI LEWU PELU.

IYE OWO EGBOGI LEOPILLS:— Ig nla sile meje alo (7/-6 pere Igo kekere sile merin abo (4/6) pere. Bere Ojulowo Egbogi miran fun orisirisi A ni a ti e ba fe ni Sobu awon:—

WATERLOO MEDICINE STORES
8 Palm Church Street Phone 22787
LAGOS Nige a, (Oja Ita Faji

ADEDUN CHEMIST
14, Wakeman Street, Yaba

---

## IWE KOSEMANI NI EYI

IWE ITOSE OHUN GBOGBO

NINU ODU MERINDINLOGUN

Iwe yi kun fun Asotele ati wipe, yio din o lowo YEMIWO" ku, nitoripe iwo na yio le ma da se AYEWO fun ara re

"KOSEMANI" ni iwe na, 2/6d pere ni a ta

ESAN KOGBOGUN SERVICE

8, Idumagbo Avenue
Lagos, Nigeria (Leti Oja Jankara)

